# Ẹni ti o n gun nkan ni o maa salamọ si ẹni ti o n rin, ẹni ti o n rin ni o máa salamọ si ẹni ti o jokoo, awọn ti onka wọn kere ni wọ́n maa salamọ si awọn ti onka wọn pọ

Lati ọdọ Abu Hurairah - ki Ọlọhun yọnu si i - ó ṣo pé: Ojiṣẹ Ọlọhun - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - sọ pe: «Ẹni ti o n gun nkan ni o maa salamọ si ẹni ti o n rin, ẹni ti o n rin ni o máa salamọ si ẹni ti o jokoo, awọn ti onka wọn kere ni wọ́n maa salamọ si awọn ti onka wọn pọ». Ati pe ninu Al-bukhari: «Ọmọde maa salamọ si agbalagba, ẹni ti o n rekọja maa salamọ si ẹni ti o jokoo, awọn ti wọn kere maa salamọ si awọn ti wọn pọ».

[O ni alaafia] [Ohun ti wọ́n fi ẹnu kò lé lórí ni]

Anabi - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - ṣe itọsọna lọ sibi ẹkọ sisalamọ laarin awọn eeyan "As salaamu alaykum wa rahmotuLloohi wabarakātuHu". Ọmọde o wa salamọ si agbalagba, ẹni ti o n gun nkan o si salamọ si ẹni ti o n rin, ẹni ti o n rin o salamọ si ẹni ti o jokoo, awọn ti onka wọn kere o salamọ si awọn ti onka wọn pọ.

https://www.sunnah.global/hadeeth/yo/show/4243

النجاة الخيرية
ALNAJAT CHARITY
لجنة الدعوة الإلكترونية
EDC E-Da'wah Committee